Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia E'oja o ta.

# ELETI OFE

A NJU WON KO SE WI L'EJO



VOL. X No. 558. ELETI-OFE LAGOS. SATURDAY. APRIL 19. 1958. KOBO MEJI (2d)

## Ejo Ijogbon Ibadan Bere, Sango W'ewon

IBADAN. Ariwo ękun lo gbo'ikan ni Kotu Onirękę nilu Ibadan nigbati Adajọ C. A. Piper sọ wipe ọpọlọpọ ohun ęlumọni ilu yi ni rogbodiyan wọn ti baję to fi ko ijọba si loawo-nara nipa idabo bo awọn ęnia, ise ti on ni lati pana irufę iwa janduku bawonni.

Adajọ Ogbęni Piper sọ wipe iduro Sango nibi isęlę na lo mu gbogbo awọn alaimọkan lokan le lati huwa janduku, bi on ko ba si fi iya ti o tọ jẹ awọn ọdaran wọnyi ki o jẹ ękọ fun awọn ęlomiran on ko ni sę isę on ni asepe.

Nitorina ki Ojo Sango lọ si ęwọn ọdun męsan, ki awọn ęnia męrinla yoku lọ si ęwọn ọdun męfa-męfa. Ojo Sango ni agbọ pe o sọ wipe ọta ibọn kole tu irun ara on.

Awọn ęnia mędogun ti Adajọ da s'ęwọn na niwọnyi: Ojo Sango, Mustafa Aiyiki; Moradeyo Akande, Lasisi Ayinla, Alimi Akanji, Salau Akanji, Sanni Alaka Olawoore Ajadi, Aręsi Ayinde; Busari Iyanda, Arasi Akande Sulemon Ajani, Adewole Alade, Lasisi Alade ati Tijani Alabi. Awọn marun ni Adajọ da silę ki nwọn ma lọ ni alafia, awọn ni:- Laditi Ajadi SalawuAkanji Tiamiyu Atobi Tiamiyu Iyanda ati Daniel Orisala.

## Oloju Ibi, Ojo Ayo



EKO. Ijọba ti sę ikede wipe ni ọjọ Tuesday ti ise ọjọ kejilelogun osu yi ni ao sę ayęyę anyọ ọjọ ibi Alaiyeluwa ọba Obinrin ilu Oyinbo Gęsi ti a nwo aworan rę pęlu ọlọlajulọ ọkọ rę ni iduro ninu Iyara igbadun ofin ni Afin Ọba, Buckingham Palace.

Ariya ayęyę ti ọjọ ibi na yio duro yio si l'ariwo ni gbalasa tęju ni ọdan lojo na.

## Iyafin Kutti Yio Sinku Adelabu



Iyafin Ransome Kuti obinrin ti ọkunrin ti ilu Abeokuta ti o si je olori kan ninu egbe oloselu N.C.N.C. yio se isinku Alhadji Adelabu, nigbati ijọba ba ti ofin makojopo kuro ni ilu Ibadan. Opolopo enia lo ti nfoju sona.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo enyin Agoju Iwe Irohin wa nile Yoruba, l'oke Oya, nile Ibo, l'oke Okun ati nilu Oyinbo wipe enikeni ti ko ba fi owo wa ranse ki osu to pari ao ko oruko re fun Loya Eleti-Ofe, ao ha se ejo ao si gba owo irin ese lowo re

## IGBIMO L. E. D. B YIO SO OBALENDE DI ILU GIDI

Ijoba so wipe ko ni si wahala tabi irejo fun awon ti Igbimo Atunluse fun ni iwe pe ki nwon kuro ni awon Ileto merin to wa lehin Obalende l'Eko. Awon Ileto na ni T'kuru, Apapa Eleko Inseru ati Igbo.

Ijoba ti wa aye sile fun won lati lo ko ile won si ni Oken. Lehinna ijoba yio tun se'we wahala ise osipo-pada fun won, awon enia ti ko ba fe lo sibi ti ijoba pese sile ijoba yio fun won l'owo ihaya ile fun osu mefa ijoba ko sini gba owo na pada lowo won.

Ibi ti ijoba pese aye na sile fun won si ni Abule Maroko l'oda okun Alagbon.

# Electricity Corporation Of Nigeria

## Sale Of Scrap Building Materials

The Electricity Corporation has for sale a quantity of second-hand building materials comprising Joinery and Timber, Corrugated Iron Sheets, Rock Rubble etc.

These materials may be inspected on application to the Inspector of Works, Building Department, E.C.N. Headquarters, Ijora.

The items will not be sold separately and contractors interested are invited to submit a lump sum tender for the whole of the materials. Tenders should be forwarded in sealed envelopes endorsed "Tender for Building Materials", and addressed to:-

The Secretary,
E.C.N. Headquarters,
Private Mail Bag 1001,
Ijora, Ebute-Metta,

and should reach his office not later than 12 noon on 28 April, 1958.

The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the highest or any quotation.

ARTHUR FAUL
Secretary

No. 73/S.2/Vol.IX/662.

# Ministry Of Economic Planning, Western Region

## Vacancies For Statistical Officer

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to one post of Statistical Officer, Grade I, and three posts of Statistical Officer, Grade II.

SCALE OF SALARY — Statistical Officer, Grade I, Scale C(E) 3,4: £744 X 30 - 834: £854 X 36 — 972.
Statistical Officer, Grade II: Scale C (E) 1,2: £390 x 18 -492: £540 x 24 - 714.

For further particulars and method of application, please see Western Region of Nigeria Gazette No. 17 Vol. 7 Notice No. 301 of 27th March, 1958.

CLOSING DATE: 22/5/58.

# Woli Adura Nilu Rossia

MOSCOW. Irohin kan wa wipe Woli Aladura kan gbe jade, ti o wipe on ti wa laiye to ogbon odun, ni ilu Moscow; ti opolopo ado nipa won tele irohin. Moto ayokele komadan ni Woli na nwo kakiri ilu pelu awo funfun awokanju loran re ogbon ti awon Sojafo.

Iwe irohin kan ti kede ijoba wipe ki awon wadi Woli apapa-adodo ti o fi arare f'oye yi. Woli na so wipe on npe iwosan, gugbon alekun erun ni iwosan re. Just nigbati o ba ni ki awon ma fi ese rin lori yinyin lai wo bata, ki awon si ma gba'wo ni Satide ati ojo osu.

## AJ'OMOGBE W'EWON

EKO. Okunrin kan ti oruko re nje Salisu Lawani ti awon fi sun esun aj'omogbe ni Adajo Kotu Asaisi fi s'ewon odun marun.

# Enia Dudu Lo Ko'se Agbe



Awon ara ile Nigeria ti o lo ko ise agbe nilu Oyinbo ni a nwo ninu aworan yi. Ogbeni Akila Todi, S.U.M. Adamawa (O. Lasg Ajele Peaue, Mallam Bomai Oga iyawo ama etsa Borsu Umoru Yola Oga akowe Kano, Saani Ahmed akowe Kano ati awon yoku.

# Enia Dudu Ntoju Omo Oyinbo



Okan ninu awon omo ile Yoruba ni obinrin ti o lo ko ise Nurse nilu Oyinbo, eyiyi ni ise Alagbato. Omo oyinbo ti a nwo yi je eyiti ko ni iya Omo Yoruba ti a nwo ninu aworan yi lo se itoju re ti o fi dagba to bi o ti to yi. A ni gbo wipe bi o ba le wo omo na ni awola, yio gba iwe eri ti yio yanju.




# Ejo Apania Bere ni Ibadan

IBADAN. Enia metalelogorun ni awon olopa fe ba se ejo apania, eyiti o sele larapa Ile Alhadji Adegoke Adelabu. Nwon so pe awon odaran na pa die ati wipe adajo ti a wa sile Ibadan ko ni le nikan se ejo na tan nitorina nwon gbe Adajo kekere ti Ikeja lo si Ibadan nipataki fun ejo awon enia na.

Esiti yio je alatako fun awon odaran na lati tako won wipe awon momo pania ni Ogbeni H A B Fasoure esiti yio si je alagborodun tabi alagbawi fun awon odaran na ni Ogbeni Mogidi Agbaje Omo 'alemi Ayoyo on pelu Babatunji Olowofoyeku.

Lojo Saturday to koja lo yi ara awon odaran ti awon fi sun wipe awon seke ba dukia eni-eleni je gbogbo won lo taku wipe awon ko jebi nipa be adajo gba idure fun won; nwon si yo ejo siro ejo won siwaju.

# Itiju Ni K'o Pa-mi Are Epe

EKO. Ni Kota Adajo Ogbeni Majekodunmi ni ose tokoja ni Odomobinrin rode-rodo kan to dabi ki a we'wo ki a to fi owo kan omo olodun mokanadilogun lojo ori to be gbaragada sekun niwaju Adajo ti o si kigbe wipe ki Adajo kuku se idajo iku le on lori ki o mase ju on s'ewon nitoripe igbesi aiye on ti bajo na ko si fe gbe'le aiye mo.

Oruko omobinrin na nje Dorcas Aregbesola ti o ngbe ona Agege ni Mushin nigbati awon fi sun esun ole pe o w'le enile lo ji aso ko ninu osu January ti odun yi.

Nigbati awon olopa ka iye igba ti Apesiadodo odelesinrin na ti lo gbewa logba awon o to omefa ogbole obinrin na ko le jiyan ni Adajo ba fi si awon osu mejila.

Itiju l'o mu ki obinrinrin na sebewiri na wipe ki Adajo kuku se idajo iku le on lori.

# Itan Isin-'ku Iya Odudua

APA 2

Lati owo Ese Ikovi

Agbo'lenu awon opitan wipe, a koiti ri, tabi ki a gburo enikan ti ojo ori re gbo to ti Iya Oduduwa. Nigbati a se abere ehin wo wipe bawo ni obinrin na ti gbe to, awon miran so wipe, o to igba (200) odun; omiran ni o to adota - lerugba odun. A ko ni le ma tele itan yi lo lesese. Ese pataki ti a fe lo ni eyi.

Ese gbogbo awon Irunmole ti pe sibi aisun Ije ti oku Iya Oduduwa. Nwon bere ere na, ni akoko, ko ledun, opolopo ninu awon Oluwoten ntoregbe, nitori aisun na ko ledun.

Nigbati o ya, ni Onigbo-gbagbo gba ilu, o si bere si yi pabe-pabo ilu na tobe ti gbogbo awon ti o ti ntoregbe tun bere si gbun wipe tani enit o nlu ilu yen.

Lale ojo aisun yi ni Gbohun - gbohun omo Oduodun bo sojo agbo ti o si nran bi owu tele-tele ota ni Onigbo-gbagbo je pelu Gbohun - gbohun na sugbon lajbikita fun enit o nlu ilu o bere si jo ijo na tikara-tikara.

Nigbati Onigbo-gbagbo yakiyesi wipe Gbohun-gbohun ni o njo, o bere si lu ilu fun bayi wipe :-

Obere gbe kete lanla
Obere gbe kete lanla
Bayi ni Gbohun-gbohun

je ijo na, titi o fi wo igbe ti o si fi jo koja enu ala araiye ati ara orun, ti ko si pada wa sile mo titi di oni oloni o ti di eni alaiiri, ohun re nikan sosi ni a le gbo, ti o ma nsin enia je gegebi ise re tele.

Nigbati nwon nse Isinku oku Iya Oduduwa, Alaketo fun oogun jo lo gba ilu lojo na, ni Alasopon ba bo sijo, ariwo nla ge-e-e, gbogbo re ndun yungba.

Ipako ni oju ti Alasopo yi gbe wa ti o fi ntiun nian ijo awon Ewele ni awon to mo, sugbon o jo ijo yi lese iyasu nigba ti

(O bere lojo ewe karun)

No. 71/S.2/Vol IX/468

# Ministry Of Economic Planning Western Region Vacancies For Statistician

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to vacant posts of Statistician in the Statistics Division of the Ministry of Economic Planning, Western Region.

Salary Scale: Scale A (I, e. £624 x 36 - 696 - 804 x 42 - 1,140 x 48 - 1,380).
Contract Scale is applicable in appropriate cases. Point of entry will be according to qualifications and experience.

For further particulars and method of applications, please see western region of Nigeria Gazette No.17 Vo. 7 Notice No. 300 of 27th March 1958.

CLOSING DATE
OVERSEAS CANIDATES 15/5/58
ALL OTHER CANDIDATES 22/5/58

# A Nfe Asoju

A nfe Asoju fun Iwe Irohin wa - Eleti-Ofe lakan awon Asoju wa ni awon ilu ti a daruko ni isale wonyi:-

Abeokuta, Ijebu-Ode, Ijebu-Igbo, Ile-Ife, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kowe si Olotu Iwe Irohin Eleti-Ofe Kosoko St, Lagos.

**E L E T I Q F E**
A-NJI-WON - KO SI SI'I L'OJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS   CABLES & TELEGRAM

28, Kakawa Street, Lagos   "ELETI - OFE LAGOS"

P. O. Box 447   Phone 22370

VOL. X. NO. 566. LAGOS, SATURDAY APRIL 19, 1958

# Akole Fi Ejo Iku Sun Lese Arun

Ona Yoruba ake wodiku wa ote yi ni a fi se ęsin oro wa lori irogie "Awe li a bi mi, Akiemorin ni a ti wo mi d'egba" ti awon Olotu egbe Alakuko ase nlori idibo wo'le awon Ile-ilmo ibile ilu ti Ijoba Iwo-Oorun sese lalpe yi, ti idibo ni ko fo'ro fun egbe Alakuko.

Eyiti o tile yanilenu ju nitti awon ilu die kan ti o ti je ibujoko pataki fun egbe Alakuko (N.C.N.C) ti enikeni ko le ni ireti wipe ibo lepa awura de nibe, ni awon ewu lile na ti to arojinle f'ori fun egbe Afenifere (Action Group).

KILO PA SABABI

Nigbati awon egbe kan ba wa ti ko ba ni ete ati iwa ododo, ti o ti wu ki o pe to, jaokulubo l'o nbe lehin iru egbe be; eyi je ise ati iwa egbe Alakuko (N.C.N.C). Eeis ko le fi ejo iku sun lese arun, aitorpe iku o lo, arun o to. Ibiti ojo awon egbe Alakuko gbe sa ni si o ye ki awon na ado si.

Oro ti wipe Ijoba Iwo-Orun lo se ofin kan ti ko jeki awon reye dibo tabi ti o se idilowo fun awon enia ipo pataki si; ohun ti a ni lati mo ni wipe kosi ighati awon enia ko ni mo oputo yato si Olotito.

Nipa eso won ni enyin yio fi mo won.

# Ohun Ti a Ba Jowo Lo Ngun



... o ba ti egbe ... nje ologbon ... a owo nina awetan yi ni Oloye wa Obafemi Awolowo pelu awon oluba-demo ... fun aijiyoro. Bayi ni Oloye Awolowo ... nitori o mo pe, enikan ko nje awa da.

Nisa awon ti a owo nlon awoçan yi ni a je ti Ologbe Bode Thomas, Oyemi Ogunmo ati Sonibare.

**PIRATE**




**SIGA TI O Gbadun**

# Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ti orun sun daradara o dara fun omu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko enin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won ti so wipe o dara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE
(Sile Mefi Abo 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lodo
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemists)
18, VICTORIA STREET, LAGOS.

## Janduku Gun Olopa Lobe Ni Onitsha

ONITSHA. Irohin ti a gbo ni lowo-lowo yi ni wipe awon janduku enia kan ti ohe gun olopa ijoba ni igba aiya nile Onitsha. Oruko Olopa ti awon gun ni ohe na nje Gilbert Eze.

Awon enia mokanla ni awon olopa ramu nitori oro yi, lati wadi bawo ni oro na ti si ki o to di ohe gigun ibi ti jamba yi gbe ti sele ni adugbo kan ti awon npe ni Oda Odepu ni adugbo ibiti awon Hausa ngbe.

Awon Olopa si nwadi kini oro na ti lo si ati tani sise buruku na. A gbo pe awon eni meta kan ti awon pe ni Odepu ni adugbo ibiti awon Hausa ngbe.

Awon Olopa si nwadi kini oro na ti lo, ati tani sise buruku na. A gbo pe awon eni meta kan ti o se pataki ni awon olopa ranse lope fun ibere nipa ohun ti o sele si olopa na. A gbo wipe ninu roju jo roju mu ni Olopa na wa nisisiyi. Ijoba nwadi lowo.

## Itan Isin-'ku Iya Oduduwa

(O bere loju ewe keta)

Alukete nfi ilu re so bayi pe:-
O ba bere ko lagege bo di.

Lagege bodi lagege bodi bi o ti nfi ina jo beni o nfi eso jo gbogbo ara re ni ojo gegebi kokoro erunkuku.

Gbogbo enia lo nfun ni gbun ti nwon si nta a lore Orisa dida o yo oju re o si fi iwaju o kuro ni awujo Ewele o si di enia. Lati ojo na ni Alaagbon ti nfi iwaju rin ma o si kuro ni awujo Oro. Isin ati ewele.

# Ita Ilu Ikoyi

**Nigbati awon Fulani ngbo irohin ilu Ikoyi gegebi o ti tobi to, nwon gbero lati gba a mo ilu Ilorin lowo oba Olu aso pelu awon tafa—tafa re lo gba Oba Onikoyi sile lojo na.**

PUBLIC WORKS



The Government of Western Nigeria regard the improvement of roads as vital in the economy development of the Region. This is shown by the £4 million Road Development Scheme now being pursued. It is estimated that work amounting to over £2 million will have been accomplished by the end of the financial year.

It is now possible to reach all Provincial Headquarters and the great majority of Divisional Headquarters on tarred roads.

Water supply schemes are pursued vigorously to provide good water for the people both in the urban and rural areas. A total of £4½ million was available for Urban Water Supplies and £450,000 for Rural Water Supplies. Amongst these are the supplies for Ishan, Auchi-Jattu, Agbor, Iperu-Shagamu, Ijebu-Igbo, Ikare, Iwo, Oshogbo-Ede, Ilesha, Effon-Alaye, Oyo, Owo, Ado-Ekiti and extensions to Ibadan and Abeokuta.

The Department has also been responsible for an extensive building programme including Parliament Buildings and the many other new buildings at Regional Headquarters.

Issued by the Western Nigeria Information Services

# Scouts Ile Gambia Njo



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon Boy Scouts ile Scotland afon fere ton Scout ile Gambia lodko ti nwon lo se ajodun Jamboree nilu Geal.

Scout ile Gambia gbadun orin ti nwon nfi fere na ko yoko ti o bere si gbe ara lokokan ti o si tuo.

# Afin Oba Ilu Oyinbo



Gbgbsa ti a nwo yi je yara kan ninu Afin Buckingham o si je okan ninu awon yara ti Oba Geal gbe ngba alejo ni gbogbo ilu re ni a ti se loso giyigiyi nidalyi

Ise lonilki oni yindin-yindin ati ogiyigiyi oni ti awon ti nyun ewa lo se loso nse ni gbogbo ara ti o nibe ninu re nkan yindin-yindin.

# Awon Oriki Oba Adele Ajosun

(1775)

Nigbati Oba Adele kiani mbe ni Badagry, o sigun lo ba awon ara Ajase ja Balogun re nigbana ni Bosunl nwon segun awon ara Ajase nwon lo si Ise nwon segun won nwon fo ilu Igangi, ati Afonyonu, O wa pada wa si Badagry o nfi won je oriki bayi pe:-

Emi adakan-lokan
Emi afija lo omo arada
Mo jare Arada mo jare
Eko Aflbosan, afi oran gbosho jare-jare
Mo pa Hausa mo jare
Hausa Tani omo oni koko loju nfi olu di
Emi apa Egun bi ani ko ba Egun tan.

Nibiti Adele ati omo ogun re gbe joko si ni Ere-lu Igboji gbe yo si won Adele ni ki Balogun mu a mu u o si beloni o si tun nfi won je oriki bayi pe:-

Mo lo Igbeji mo jare
Igbeji awon tani Erelu nfi oju di.

Nigbati Adele tun ate alwaje o ba Ilu Iwoye Ilobi ati Ilero jagun o si segun won nigbana lo nfi won je oriki bayi:-

Mo je Iwoye tan
Mo gba erekun Ilobi
Emi singun gba oni yowo

Lehin ti Oba Adele ti gba awon eeba kuro lowo awon Ilobi tan awon bere lowo re perkiri o fe gba o si dahun pe, oti ko fe akokan ibe on ti on fe elgelli awon ma ki on ni oriki bayi pe:-

Emi ogbogbo ti ngba ara adugbo Mo gba Somoye mo gba Apati Mo gba Sodeke tomo-tomo,
Agelebe-koro-jaujan
Agba ko si ilu baje
Bale ile ku ile dabore.

# EMa Ka Iwe Iro-hin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re.

# Egbe Meso Pari Ija

EKO Ija pari, ki olenu so omo ki omwn so iwa hu; o to si wa leti fereti wipe tembelekun kan ti o ti be sile larin awon asamegin egbe oloselu pataki nilu Eko ti pari.

Nigbati ota yi koko be sile larin awon egbe yi a gbo wipe awon apakan dite lati yan Olori egbe miran dipo Mayor won sugbon okiki Mayor yi ti po tobe ti awon ko le yo ni Olori.

Won ti mu ese odun ti awon so oruko re ni "Meso gba Oninin" Sugbon awon yio yi oruko aso na pada si "Meso Pari Ija".

# Tale Ma R'opo Adelabu



OLOYE K. BALOGUN

Eniti a nwo yi ni Oloye Kola Balogun, eni ti a gbo wipe awon awujo egbe N.C.N.C. ti o mbe ni egbegbe Iwo-Orun, Nigeria nreni - rojufun le lori lati gbe si ipo Alhaji Adegoke Adelabu ti o s'alaisi.

Enia meji ti awon tun ogbero kanna le lori ni Ogbeni J.O. Fadahunsi ati Ogbeni T.O.S Benson A koiti mo eniti nwon o yan ninu awon meteta ni pataki.

# Nwon Ri Epo Nilu Ituk

EKO. Awon Oyinbo Onisowo Epo Shell B.P, ni nwon se ikede wipe awon ri epo nina ile ti nwon ngbe nilu Ituk, ile awon Calabar.

Nitorina, nwon yio tun gbe ile siwaju si lati le mo bi epo na yio ti po si ki odun yi to pari.






Awon gbajumo enia gba wipe gerebi mo ti je ogn ako ile, mo mo okan ti awon enia fe, mo si le so wipe Oti Star ni enikeni feran ju.

O da mi loju, ko si eniti o le m'oju kuro ninu adun Oti Star, ndara to be ge, o si lagbara pelu. Tabi iwo yio tun fe si i?.

STAR



OTI STAR

Fo le eviti odara ju! Beni Sammy Sparkle wi.

Awon ohun elo to dara jul



ni aiye, Eso oka barley to l'arun daradara ni a fi se Oti Star, awon enia ti o loye lori pupo l'o nse Oti Star, o mo, o si ni aro to yayi.

Oti Star nse orisirisi: adun re ko si legbe.

## Gomina Ogba Gba Isinmi



Lehin ti Gomina agba Sir James Robertson ti pari irin ajo re tan, ati lehin kakiri ile Nigeria tan lo ge-ge wa bere ajo isinmi olofe [illegible] ti yio ma se lo titi yio fi pada de. Ajo adura, abo alafia [illegible]

## Ijoba Faranse Fe Dan Eru Oloro Wo.

JAMANI: Inebin kan wa lati odo awon omo wa ti o nkeko nilu Jamani wipe Ijoba Faranse nse igbiyanju lati lo so eru oloro (Atomic Bomb) si arin okun yanrin (Sahara Desert) emiken ti mo bi eru oloro na ti buru to.

Nigbati awon Amerika ju bombu eru oloro na si agbami okun ti o jinna si wa dara dara, ninu okun Pasifiki (Pacific Ocean), ogorun ona ti koi ti ho kuro ninu amedi ti oruku eru oloro na gbe wa sita na nihin. Itesi opolopo awon omo Ilewe ni yio mo bi okun ti a daruko yi ti jinna si ile Afirika to.

Awon ologbon so fun wa pe lati ile Afrika si Japan jinna to egbaa-marun ibuso (10,000 miles) Lehin na ni a tun ma kan okun Pasifiki ti awon ti dan eru boruku na wo ni-nu osu September; odun tokoja sibe gbogbo aiye ni eru na da lamu o ohun-hun ibiti o wa nitosi wa.

(Koi ti pari)


**Kere o!**

Ati ni original ogun German to sese de, fun oyunu atan tokunrin obinrin. Tete wa ra tire e'e to tan.

**S. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.


## Barklays Bank Embarks On Africanisation Scheme

A new training scheme has been initiated by Barclays Bank for their African staff in Nigeria and Cameroons.

The main objective of the scheme is to give Africans employed by the bank a thorough background in the theories and practice of banking to make them fit for executive posts. This AFRICANISATION Scheme will provide up to two years' intensive practical training in the United Kingdom for selected staff who fulfil the following requirements:

1. At least two years' service with the Bank in Nigeria.
2. Completely satisfactory reports throughout service with the Bank, including reports from the Banks Training Centre in Lagos if applicable.
3. A minimum of two compulsory subjects passed at one sitting, in Part I of the Banking Diploma examination of the Institute of Bankers.
4. Under 30 years of age.

During the period of attachment to one of the United Kingdom Branches of the Bank, trainees will be required to perform clerical work, and by studying in their spare time will be expected to complete all the obligatory subjects of Parts I and II of the Institute of Bankers examinations within the period of two years. Trainees may also be expected to attend courses of training in the United Kingdom. The training period may be terminated if reports on a trainee's work and conduct are unsatisfactory, or if insufficient progress is made with the Institute of Bankers examinations.

The cost of return air passages to the United Kingdom at tourist rate will be paid by the Bank and accommodation with full board will be provided for the trainees in the United Kingdom at the Bank's expense. Travelling expenses to and from the branch at which the trainee is employed will also be paid by the Bank. Trainees will be paid their Nigerian emoluments during the period of training and those stationed in London will also receive a London allowance at the rate of £65 per annum. A kit allowance of £50 will be payable to each trainee on arrival in the United Kingdom.

Those who complete Part II of the Institute of Bankers examinations will be placed on a special list and will be considered for promotion in preference to others.

Barclays Bank is the first Banking House in the Federation of Nigeria to evolve a comprehensive training policy for Africans to enable them work side by side with their English staff in the United Kingdom Offices.


**M.B.T.**

(MAGIC BLOOD TONIC)



Inú dé, òkùnkùn parada. M.B.T. dé, òkùnrùn ṣó lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sàré oyi pòsẹ̀. Ara bùburú wọ̀gbọ̀, lailesan pẹ̀hìn-ẹ̀kùn M.B.T. [illegible] ti amú ni jeun b'ikan, [illegible] bi ọ̀kùn, amú ni tọ̀ bi [illegible] Abiwéré [illegible] [illegible] ko si pérétí nlo o. [illegible] pẹ̀lú [illegible] owó-gbọ̀.

ARADAN STORES P.O.Box 2 EBUTE-METTA.






"HIS MASTER'S VOICE"

Distributed by The United Africa Company of Nigeria Limited


Printed & Published by The Daily Printing and Publishing Company 38, Kosoko Street P.O. Box 547 Lagos Phone 21370